SANGBA FO AKARA TU S'EPO NILE IBO



AWOGBA
Omode fun
Girl, Kyt,
Hihu-chin,
Orere,
Ra Tire Ni
Ile Egbogi
— ISE —
Olodumare
Okebola,
Ibadan,
116, Great
Bridge St.,
LAGOS

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

TO CLEAR

Gents Suede Court Shoe
Brown, Black & Grey
Before 50/- Now 42/6

Obtainable at :-
A. B. AKINYEMI
10A Moloney Bridge
LAGOS.

VOL. No. VIII 478. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, JULY 28, 1956. KOBO MEJI (2d.)

# Sangba Fo Akara Tu S'epo Nile Ibo

EKO.

Irohin ọkan-ko-jọkan ni ati ngbọ lati ilu Oyinbo wa lori ọrọ gbohungbohun lori ede ko yede kan ti o bẹ silẹ larin ogbogi oṣelu kan ni ilu yi ati Sẹkitẹri agba ti ilu Oyinbo lori ọrọ owo girimọyan kan ti ako si ile ifi owo pamọsi ti anpe ni African Continental Bank.

Sẹkitẹri agba ti paṣẹ wipe ao ṣe iwadi ọrọ yi, o ti yan oluwadi. Adajọ agba Ọgbẹni Sir S. Foster-Sutton ni yio ṣe alaga iwadi na.

Ọrọ yi ti bi ige o si ti bi adubi silẹ l'arin Sẹkitẹri agba ati awọn oṣelu Ila-Orun.

Lori ọrọ yi ninu ile Igbimọ ilu Oyinbo ni Sẹkitẹri agba ṣe alaye wipe on fẹ ṣe awẹmọ nipa owo ti nwọn ko si ile Ifowopamọsi na ati gẹgẹbi ọrọ na ti kan Ijọba Ila-Orun, on si ni ireti wipe awọn Ọlọla Dokita Nnamdi Azikiwe pẹlu awọn isọngbe rẹ yio gba bẹ, nitori anfani ti wọn ati ti ilu Nigeria.

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited.

Ile Ifi Owo pamọsi yi
Nfi ọna owo han ẹni
Bi o ba fẹ jẹ onișowo pataki ao
ran ọ lọwọ nipa wipe ao tọ ọ
si Ọna ti o dara, ao la oju rẹ
si Ọna owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni a tun nṣe iranlọwọ fun
gbogbo ọja ilẹ wa ti anta si agbaiye.

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London B. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London B. C. 4.

# Ohun ti ijoba se yo Oba Olobi

Agbọ ẹjọ enikan da, agba Osika ni Oluwa rẹ, ọpọ enia ni yio ti gbọ wipe ijọba Iwọ Orun gba ade kuro lori ọba Olobi ti ilu Ilobi. Bi enia ko ba gbọ tẹnu ẹga, yio wipe nṣe ni ẹga npa-ato. Bi ọrọ na ti lọ niyi.

Ọba Olobi ti wa ni odekoyede pẹlu awọn ara ilu rẹ ti pẹ. Lọdun 1951, lasiko awọn Atinga a gbọ wipe o lọwọ ninu iṣẹ awọn ẹgbẹ na, tobẹ ti nwọn fi ba ṣe ẹjọ ninu kotu, o si jẹbi ọrọ na labẹ ofin amunimuye (Criminal Code Section 365 ati 406) Nitori idi eyi Ajẹlẹ agba ni Abẹokuta sọ wipe, o yẹ ki i ijọba da a duro ni igbimọ ijọba ibilẹ.

Ijọba daro lasiko na wipe, o yẹ ki a gb'ade kuro lori rẹ pẹlu ijọba tun daro gẹgẹbi ọna ofin wipe niwọn igba ti ijọba ti da a duro kuro ni igbimọ, ko tọ ki a tun gbade kuro lori rẹ mọ.

Nigbati nwọn da igbimọ Ẹgbado ati Ifọnyin silẹ, Ọba Olobi ilu Ilobi jẹ ọkan ninu wọn lọdun 1953. Ṣugbọn igbimọ kọ lati gba Adebọwale si igbimọ wọn, ayafi ki nwọn ri iwe lati ọdọ alaṣẹ ijọba ibilẹ.

Gẹrẹ ti mo bẹrẹ iṣẹ ni Ibadan ni Adebọwale ti ntọ mi wa fun ki nle da on pada sinu igbimọ ijọba ibilẹ, mo wi fun pe ko nṣe ẹjọ mi, ọrọ ti awọn enia pataki ninu igbimọ ni lati joko sọrọ le lori ni. Bi awọn enia ba fẹ ọ pada ngo jẹki ijọba gba pada si igbimọ ati sori oye rẹ, o sọ fun ni pe ọpọ enia lo nṣe ti on lasiko na. Mo yan Oyinbo Ajalẹ lọ si Ilobi lati wadi kini awọn en'a nwi nipa pipada Ọba Olobi ni 1955, Ajẹlẹ si fi ye mi pe pupọ ninu awọn enia ilu na lo tako pipada bọ rẹ. Ọpọ iwe ni mo rigba ti nwọn fi mbẹbẹ, Olobi funra rẹ kọwe si mi.

Mo tun ran Ọgbẹni D.S. Adegbenro lọ si Ilobi lati bere ni igbimọ wọn bi awọn ba fẹ ki Adebọwale pada sori oye rẹ. nko jẹki enikan ni mimọ ibere yi tẹ'ẹ, nṣe ni gbogbo igbimọ kọ jalẹ-jalẹ, eyi ka mi lọwọ ko lati ṣe ohunkohun nipa Adebọwale.

Lọjọ keta oṣu June 1955, Ajẹlẹ Agba kọwe ranṣẹ si ijọba wipe, iwa ti Adebọwale nhu kakiri ilu tilẹ tunbọ wa buruju, on ro o si ẹtọ wipe, o yẹ ki a gbade kuro lori rẹ, ki a si wa a kuro nilu.

Ni ọgbọnjọ oṣu Jan. 1956, awọn enia kan wa ba mi ni alejo nwọn wipe awọn ni Afọ-aj: ... Ilobi awọn ti yọ Adebọwale kuro ni Ọba Ilobi gẹgẹbi eto ati aṣa ibilẹ, awọn si fẹ ki ijọba ba wọn lọwọ si.

(Wo yoku loju ewe kejọ)



Mr. Thomas Monson (right) the Public Relations Officer of the Corperative Supply Association who is Mr. Ogunwale's American Counterpert in Nigeria was met at Ikeja Airpot on his arrival by Mr Oladipo Batoye, General manager of the Coop.

A Nigerian co-operative employee has been working with an American cooperative since last April as part of a two-year programme to learn more about how American cooperative function.

He is Mr. Samuel T. Ogunwale of the Co-operative supply Association Limited. The American co-operative is Group Health mutual and Group Health Association which provides insurance against illness, accident and death for 160,000 persons in an area approximately the size of Nigeria.

Mr. Ogunwale arrived in New York on April 20 and spent four days in Washington at the Public Relations Conference of the Co-operative League of the United States of America. In New York he was entertained by Oliver Edmund Clubb, former chief of the far Eastern section of the American State Department.

Mr. Ogunwale has two main impressions about America which are different from what he had expected. First, the discrimination against people of colour in the three places he has visited is not what he had been led to expect. "There was no discrimination in the hotels and eating places, on the trains or on the airplanes," he said.



Mr. Samuel T. Ogunwale (right) receives a cordial welcome to Minnesota from Minnesota's Democrat - Farmer - Labor Governor Orville L. Freeman (left), in the Governor's office in St. Paul. with them is Mr. Geo. W. Jacobson, Group Health general manager and sponsor of the exchange of personnel with the Nigerian Cooperatives.

In Minnesota he learned there is a law forbiding discrimination against racial minorities in employment and a commission to protect such minorities.

The second impression is the extent to which socialist ideas prevail in American business life. In Washington he met the government official who is resiponsible for promoting cooprative housing and a representative of the government department that sponsors rural electric cooperatives to carry electricity to farmers. He learned that the government sponsors cooperative credit organisations for farmers and city people, finances public housing which is built by the cities for low income families, sponsors and finances hospital construction and education, provides old age insurance, carries on research in business, science and health.

He found that in Minnesota which is the foremost cooperative state in the United States a large part of the farm supply and form marketing business is carried on cooperatively. Diary products such as milk, milk powder, butter and cheese are produced or processed almost entirely in cooperative factories, while other cooperative factories dress and freeze poultry grind grain for stock feed, make flour for macaroni and spaghetti, generate electricity, butcher, dress and freeze beef cattle and hogs. There are cooperative hospitals and health centres, cooperative stores dealing in food, clothing, hardware, house-hold appliances, farm supplies and farm machinery, cooperative auto agencies and auto services stations, cooperative grain depots, cooperative livestock yards, cooperative wool marketing agencies, cooperative freight lines etc.

The extent of cooperative activity and the extent to which the goverament promotes social projects, says Mr. Ogunwale, give a picture of socialist activity not generally understood abroad.

## Isele ja nilu India

INDIA. Laipẹ yi ni a ṣe irohin nipa iṣẹlẹ kan ti o ja nilẹ Greeki lati ori oke kan ti a npe ni Fisufiọs (Visuvius)

Bakanna ni Isẹlẹ fun ja nilẹ India lati ori oke ilu Ahmedabad; iṣẹlẹ to ja nilu yi le ke-ka.

Enia mẹtadiladọrun lo ku de ọrun ninu iṣẹlẹ na, ọgbọn enia lo poora ti a ko ri oku tabi aiye wọn iwọn adọta lerugba enia lo fi ara ṣeṣe.

Ilu kan ti a npe ni Anjar ni iṣẹlẹ yi gbe ṣe jamba pupọ, iwọn ẹgbẹrin ile lowo danu, o fẹrẹ dahoro.

Ati nilu kutch igba ile pẹtẹsi nla-nla lo wo danu, bayi ni awọn ilu ti o mbẹ ni agbegbe Ahmedabad fẹrẹ di ahoro.

Ki Ọlọrun maṣe jẹki a mọ ohun ti nwọn npe ni iṣẹlẹ lapa ilẹ wa nihin.


Mo Gbadun Siga

Pirate




Ni Siga To Dara

## Oju fun oju, ehin fun ehin

ABẸOKUTA. Alaiyeluwa Sir Ladipọ Ademọla, Alake Abẹokuta lo sọ wipe, a ko npa ọmọ jaiye, ẹda to ba pa enia ni ori rẹ ni a o ti mu ida kọja.

Ọba yi dupẹ gidigidi fun Igbimọ House of Lords ti nwọn ko iru ofin buruku yi jalẹ. Bi iru ofin yi ba lọ ṣẹlẹ ni totọ, ipania ati itẹjẹ silẹ yio wọpọ ni bi gbogbo, ogun jija yio si wa. Ako ni le rin bi a ti fẹ, ko ni si alafia larin ilu ati lẹhin odi, yio di wipe bi enia meji ba ti ṣe gbolohun asọ nṣe ni nwọn yio ma pa arawọn, Mose Olofin-Israẹli ṣe ofin wipe oju fun oju, ehin fun ehin. Ṣugbọn nighani, ẹni ti o ba pania gbogbo ara ile rẹ ni a o pa

Nilẹ Nigeria loni, inu buruku ati owu jijẹ pọju, bi ko ba si ofin yi, ipania iba wọpọ.

EDITOR

Lati kin Alaiyeluwa lẹhin, ẹ wo aiye igba lailai, nigbati koiti si ofin fun ipania nigba na, bi awọn alagbara ba ri ẹni ti nwọn ko fẹ, nṣe ni nwọn o bẹ ori rẹ fun orișa Ogun.

## Odun Ileya ko Larinrin

EKO. Nigbogbo ọdun ti nwọn ti nṣe nilu Eko, ọdun ti ọdunni lo yakọ.

Bi nwọn ba nṣe ọdun nilu Eko, nṣe ni iro ilu yio ma dun lọtun, losi, ti gbogbo awọn enia ati awọn ẹlẹgbẹjẹgbẹ yio majo bi kokoro ṣugbọn lọdunni, a ko tilẹ gbọ konkolo ilu rara.

Laseko ọdun, yala ọdun ti Awẹ tabi ti Ileya nṣe ni ẹsẹ girigiri awọn enia ko njẹki Mọto ri ọna gba kọja. Ṣugbọn lọdunni ko ri bẹ rara, agbara kaka lafi ri to iwọn igba enia loju opopo, ohun to jẹ wipe iwọn ẹgbẹrun enia yio ma tọwọ lọ si ọdun. Awọn enia to kirun ọdun fẹrẹ ma to irinwo.

Aṣa awọn Oṣugbo mọnimọni nigbati ẹnikan ba jawe ninn wọn nwọn o ma lulu bayi pe "Kilopa Ọgbẹyi lo pa a" Ohun to da eyi silẹ ni wipe ọpọlọpọ awọn ara ilu Eko lo ti lọ ṣe atipo ni Surulere ati pe ai ko si owo ati ọfọ iku awọn enia to pọ nilu. Nkan to fa a niyẹn.

## Lagos Central Planning Scheme, 1951


# SLUM CLEARANCE

Application for ex-gratia compensation.

The Committee which has been appointed by the Minister for Land, Mines & Power is now prepared to consider applications for ex-gratia compensation from:—

(a) Any person who, through operation of the Slum Clearance Scheme is deprived of an income arising from property in the Scheme area, and is left with insufficient income for the support of himself and/or his dependants; and

(b) Bona fide traders and businessmen who are deprived of their place of business as a result of the Scheme.

2. Applications must be made on a form which can be obtained from the Lagos Executive Development Board's Offices.

3. Closing dates for applications:-
Completed application forms must be returned to L.E.D.B. Offices on or before the following dates:-

FOR SUB-AREA N0, 1 OF THE SCHEME 31st JULY, 1956
FOR SUB-AREA N0. 2 OF THE SCHEME 15th AUGUST, 1956
FOR SUB-AREA N0. 3 OF THE SCHEME 30th SEPT., 1956.

4. Temporary shops will shortly be built close to the Scheme area. Displaced businessmen and shop-keepers who wish to be considered for these should apply to the Lagos Executive Development Board.

5. Further information can be obtained from:—
L.E.D.B. Offices, Reclamation Road, Lagos, from 8.00 a.m. to 2.00 p.m. daily
or
L.E.D.B. Information Office, Broad Street. Lagos from 12 noon to 2.00 p.m. and 4.30 p.m. to 6.00 p.m. daily.

C. S. CLOVER
CHIEF FEDERAL LAND OFFICER
Chairman, Ex-Gratia Compensation Committee.


## Oro Alafin Di Oro Esin

ỌYỌ Ọrọ ọtẹ Alafin, Ọyọ Alhadji Adeyẹmi keji ti o nja ranyin nilẹ ti yi kuro ni ọrọ ilu, o ti di ọrọ ẹsin nisisiyi.

Awọn Imale Ọyọ ti da si meji larapa ọrọ Alahadji Alafin awọn apakan fi ara mọ ti ọba na wipe ko pada wa sori ọba ni nwọn fẹ. Awọn apakeji si fi jaguda pali le wipe, ati oku ati aye rẹ, awọn ko fẹ ẹ mọ li Ọyọ.

Nitori idi eyi, ẹsin Imale da si meji nilu Ọyọ, Awọn ti ko fẹ ki Alafin Adeyẹmi keji pada lọ kirun ọdun ti nwọn lọtọ, Lemọmu Ganiyu ilu Ọyọ lo kirun fun wọn. Ṣugbọn awọn to fi ara mọ wipe ki o pada si ori itẹ lọ kirun ti wọn l'ọtọ.

## Gramma Yoruba

Ẹnyin ọkawe Eleti Ọfẹ, ẹ jẹki a ṣe idanwo yi, lati fi mọ bi ọgbọn wa ti pọ to ninu ede Yoruba, ko maṣe jẹ wipe ede Oyinbo nikan ni ao ti pẹlẹ mọ.

Apẹrẹ niyi. Ṣe itumọ ọrọ yi ni ede Oyinbo si iyẹ ọna mẹrin pataki ti o jẹ noun. Owo. Idahun rẹ niyi:- Owo-Money, Owo-Trades, Owo-Horns, Owo-Sun.

1. Ṣe itumọ Ojo si orișì ọna mẹta noun.
2. Ṣe itumọ Ogun si orișì ọna marun to jẹ noun.

Ẹni ti o ba fesi, ki o fi ranṣẹ si

Lemọmu Ajakuta
c/o Eleti Ọfẹ
28 Kosọkọ St.
Lagos, Nigeria.


# ABOKI



JẸ AWOGBARUN to LOKIKI KA ILẸ ENIA DUDU.
AJẸBIDAN ni fun IKỌ, LAKUREGBE, IWORA, AKOKORO, SOBIA, AKANDUN, JẸDIJẸDI, etc.

KOṢEFẸKU ni GBOGBONṢE yi jẹ fun GBOGBO ILE ntoriaa RA IGO kan LONI Lọdọ:-

IBUKUN - OLU MEDICINE STORES,
Amunigun Street, Box 245, Phone 189x, IBADAN
E 21, Sabongeri, ZARIA, X 5, Central Market, Box 2205,
Kumasi, Gold Coast.



## Lagos Executive Development Board

Lagos Central Planning Scheme

# SLUM CLEARANCE

## Notice To House Owners

It is notified for public information that by Order in Council made under the Lagos Central Planning Scheme the portion of Central Lagos described as SUB AREA 3 will become vested in the Lagos Executive Development Board as from August 1st 1956.

2. Sub Area 3 as defined on Plan No. L.T.P 840 which is open to public inspection in the Town Planning Branch of the Lagos Executive Development Board, in Reclamation Road, Lagos or at the Lagos Executive Development Board, Broad Street Office, Lagos, is bounded by the following Streets:-

In the North - by portion of Palm Church Street
" East - " " Martins "
" South " " Breadfruit "
" West - " " Balogun "

J. W. Henderson
Chief Executive Officer
20 : 7 : 56.

Reclamation Road,
Lagos.

# ELETI ỌFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS — CABLES & TELEGRAMS

28, Kosoko Street, Lagos
P. O. Box 467

"ELETI - ỌFE LAGOS"
Phone 23370

VOL. VIII. NO. 478, LAGOS, SATURDAY JULY. 28, 1956.


## Egbe Alajumo-Sepo (Co-op) Ndabira

Awọn ẹgbẹ alaṣepọ-owo (Coop) nda bira, ni gbogbo ọna ti nwọn fi nṣe iṣẹ owo wọn lai duro lori wipe awọn nwa ere jẹ lori awọn ọja ti nwọn n t a, bikoṣe fun ire ati anfani awa enia ilẹ Nigeria ni ohun pataki ti ijọba ipinlẹ Iwọ-Orun (Action Group Government, Western Nigeria) fi ṣe idasilẹ iṣẹ rere yi. papa fun awọn Agbẹ Onişẹ ohun ọgbin oko.

"GELE KO DUN BI K'AMOWE

Ki ari owo ra ẹlẹya ko dabi ki o yẹni" ni owe awọn Yoruba mọnimọni ti o wa si ọkan wa nigbati a fi oju inu wo iṣẹ ti awọn to mu o p o i j ọ b a Ipinlẹ Iwọ-Orun dani, oriṣiriṣi iṣẹ ribiribi fun anfani awọn enia ipinlẹ Iwọ-Orun ati fun gbogbo ilẹ Nigeria wa yi, ma ki a sọ laifọtape wipe irufẹ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ pẹlu awọn aworoṣaṣa isọngbe rẹ (Ministers) jẹ awọn ọjọgbọn enia ti o nfi ifẹ ilu ati awọn enia ilẹ Nigeria ṣiṣẹ fun ire idagba s'oke ipinlẹ Iwọ-Orun ati ogo gbogbo ilẹ Nigeria.

Eyiti o jọni l'oju julọ nipe awọn ẹgbẹ Alafọwọ-sọwọpọ (Cooperative Supply Association) ṣiṣẹ yi tun mu ifọwọsowopọ wọn na de ilu Amẹrika n i p a piparọ awọn oṣiṣẹ larin ẹgbẹ ti ilu wa nihin pẹlu ti awọn Amẹrika l'ọhun gẹgẹbi irohin ti a ṣe si apakan Iwe Irohin wa yi niba ṣoki lati fi han ẹnyin ọkave wa wipe awọn ẹgbẹ alafọwọ-sowọpọ ş'owo nşe ohun ara nilẹ Nigeria.

Abọ ọrọ to fun ọmọluwabi.







### IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ e w a ra ỌMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

ỌMỌRELA BABY MIXTURE
(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)
O wa Lọdọ :—
COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS


## Oluwole se ikomo to Larinrin

ABULE OKO. Lọjọ kẹjọ oşu yi ni ọgbẹni D. S. Oluwọle şe ikomọ ọmọ ọmọ rẹ ti a npe ni S. O. Oluwọle. Iyawo rẹ Ribẹka Sanyaolu lo bi ọmọ titun na, a si fun ni orukọ lọna ti Igbagbọ bayi pe "Abọlade Arẹmu Oluwọle'

Bakanna ni awọn Imale tun şe Suna fun ọmọ yi kanna nwọn fun ni orukọ yi Jimọ Arẹmu Oluwọle. Alaga ikomọ jade na ni Ọgbẹni Jọlaoşe Bọlẹ.

Awọn toşe ipese ohun jijẹ ati ohun mimu lọjọ na ni Iya Afin A. A. Taiwo Ọlatowun ati Ọlatunde. Alufa ti o wa şe suna ọmọ na ni A l u f a Ọrẹ.

Gbogbo w ọ n ni jijẹ ati mimu tẹ lọrun. Diẹ ninu awọn e n i a ti aye wa lati darukọ to wa sibi ikomọ na ni Sariyu Oluwọle J. Pẹlu Abusatu. Nuratu Ọlayinka Ọlọlade Şiwọku O. Allen ati ọpọ enia to wa lati Eko, Abẹokuta, Ibadan, Ẹgbẹ S'orogun - dẹgbẹ şe bẹbẹ nibẹ. Ọlọrun ko fi ire ọmọ kari wa bayi k'o si da ọmọ na si. Amin.


SECONDHAND PRINTING PLANT

Foolscap Folio Cropper
TREADLE £85.
11" x 7" Hand Platen £57
Aldershot Warehouses,
Pound Road,
Aldershot, England.



YOUR ENGINE MAY BE MORE POWERFUL THAN YOU THINK!

I.C.A. UNLOCKS ALL THE POWER IN YOUR ENGINE

Only SHELL has ICA

IGNITION CONTROL ADDITIVE
(incorporating tricresyl phosphate)

THE MOST POWERFUL MOTOR SPIRIT YOU CAN BUY

## Irora Lakuregbe

Iwosan rẹ lododo niyi. Bi enia ba nfẹ iwosan ti o daju kuro ninu irora Lakuregbe, o yẹ ka tete fi egbogi yi ko loju. Nitoripe Kindierin oluwa rẹ ko ṣiṣẹ to o nfẹ iranlọwọ. Nitori iru amọdi bayi lati ṣe ṣegbogi DE WITTS, yio si fun enia ni igbadun ara

Kakiri aiye ni egbogi yi ti nṣe iwosan Lakuregbe, danwo, ki o lọ ra ọkan ni ṣọbu egbogi.



Ohun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba sise tara, sugbon bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio desi oluwa re, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti sise. Danwo lo ra ni sobu egbogi.

**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles



### Now Available

BUGLES, BEDSTEADS, PAINTS, DISTEMPERS SAFES Etc.
Just Write, Call Or Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**

20/28 BALOGUN STREET (P. O. BOX 395) LAGOS. and NEW COURT ROAD. IBADAN



### Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to ṣeṣẹ de, fun onirurụ aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**
MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos


# Ikilo Ahun Ajapa

Ajapa dide duro larin Aiọ igbimọ, o wipe, ẹnikeni ti o ba mbọ wa ki mi ti ko ba gbọ ariwo, ki o maṣe wọle ṣugbọn bi ariwo ba wa, k'o ma bọ wa.


## Kiniṣe ti inu awọn Ẹbi Ogbe* fi ma a ndun!






EBI Ogbe ngbadun OVALTINE lojojumọ. Eyi ni afikun onjẹ to nfun wọn ni ilera. Bi enia ba fi OVALTINE ṣe onjẹ arọ yio fun u ni agbara ati okun ti yio le fi ṣe iṣẹ ojọ. Ti o ba mu lale yio fun o ni agbara ti oti lo sẹhin pada, yio si tun fun ni ilera, ọkan rẹ asi fuye, wa si sun gbadun. Fi OVALTINE kọra ni mimu wa si ma a gbadun!

* [illegible]

**OVALTINE**




*–ko si ohun ti o dara to!*

OWA 1956

## Ina Jo Enia Merin Pa

BENIN. Awọn onișẹ ako - Rọba mẹrin ni a gbọ wipe ina jo pa sinu ile ni Abule Igo, niwọn ibușọ marun s'Ilu Ibini ni ọjọ Monday ọsẹ yi.

A gbọ wipe awọn enia na da ina sinu ile ikin ti nwọn fi nyan Rọba ti wọn ti ko, awọn na si sun sinu ile na. Rọba ti nwọn nyan na l'o gb'ina ti jamba yi fi șẹlẹ.

Eniti o șikarun wọn ti ina jo pẹlu awọn mẹrin ti ina na jo pa d'oku ọrun mbẹ nile Iwosan fun ipalara pupọ ti ina șe fun u.

Lọwọ iku ina, Oluwa rere gbawa.

WỌLE-WỌLE ILE BABA ỌMỌ KI BA ỌMỌ LẸRU, WỌLE.

EKO- Gbukẹ ni a gbọ ni ọjọ Monday ti ișe ọjọ kẹtalelogun oșu July 1956, [illegible] fi ige [illegible]

Gẹgẹbi a ti ri ẹjọ na si ni wipe Onitọlọ ko ni ẹtọ lati ko si inu iga nigbati oye ko ti kan ni jijẹ ati pe ko si ni ẹtọ lati ko si inu iga nigbati awọn ẹbi rẹ ko ba yan fun oye jijẹ.

## Okunrin Kan Ra Apola Igi Ni Eja Panla

AWẸ ỌYỌ. Obinrin ijoye kan l'ọna ilu Awẹ ti a npe ni Subuọla lọ ra ẹja panla nilu Ibadan. Nigbati o npada bọ nile, mọto wọn ku silu Ojọọ, lati agogo mẹwa owurọ ibẹ ni nwọn wa gbogbo awọn mọto ti o nkọjá lọ si ọna Ọyọ ni o ti kún fun awọn ero ti o nlọ șe ọdun nile, eyi ni kojẹ ki nwọn ri mọto miran wọ.

Subuọla ẹlẹja Panla ri ọkunrin arugbo kan ti o ru apola igi wa si ọja o ra si ko le ori ẹja Pa'nla ti o lọ pin ni Ibadan.

Mọto na gunlẹ silu Awẹ niwọn agogo mẹjọ alẹ ọkunrin ti o ri ẹja yi nigbati nwọn gbe silẹ ni werewere oju alẹ ra ọkan ninu ẹja na lọ sile. o gee, o si se e l'ọbẹ.

Ọkunrin na ti jẹun yo tan kin to wa ri pe apola igi ni on ra. Alufa Șọși kan ti o gbọ nipa ọrọ yi, ti o si jẹ aladugbo fun ọkunrin to ra Panla, gba nimọran pe, ko gbọdọ ma lọ rohin fun awọn Olotu ijọba bi bẹ kọ yio șe ara rẹ leșe.

## Eyiyi na ma se kelemo o.

OSHODI. Obinrin gbajumọ kan nilu Oshodi ti a npe ni Iya Afin O. T. Kalẹ ni ẹniti mọto Akẹro kan ya bara kero loju ọna ti o si lọ rari mọ ogiri ile Iyafin na tobẹ ti ogiri ile na fi wo lu ọmọbinrin ti iya na bi mọlẹ ni biti o gbe nkọ ẹkọ rẹ lọwọ.

Omi eyiyi na koiti gbẹ lori iya yi tan ti mọto Akero miran tun fi oju ọna silẹ ti o tun lọ rari mọ ile obinrin yi kanna, șugbọn lọ tẹyi, ko si ipalara fun ẹmi enia, Eyi [illegible] na ma kuku [illegible] iku ojiji ki Ọlọrun rere gbawa. Ọlọrun ko rọ iya na loju o.

### OHUN TI IJỌBA ȘE YỌ ỌBA OLOBI

(O bẹrẹ loju ewe kini)

Mo tun ranșe si D. S. Adegbenro ki o lọ silu Ilobi lati șe ayẹwo bi o ba jẹ wipe nitotọ ni awọn to wa na jọ afọbajẹ ilu Ilobi, o si mu esi wa wipe afọbaja ni wọn nitotọ. Eyi mu mi gba wipe ko nșe așa ati ofin ișẹdalẹ nikan lo yọ Adebọwale ni ọba, șugbọn nitori ki alafia le wa nilu, o yẹ ki a yọ ọ kuro ki a si wa lọ.

Bayi ni ijọba ba fi așẹ si iwe ti mo kọ pe ki a yọ Adebọwale ni ọba olobi ilu Ilobi. Nko șe iwe wipe ki a wa a kuro nilẹ Egbado, șugbọn gẹgẹbi o ti wa nilẹ Ẹgbado na ti o ba nhu'wa ti Gomina ba rope yio di alafia ilu lọwọ ati ijọba tere, nigbana ni ao șe iwe ti ao ș gbe lọ jina silẹ Abẹokuta ati agbegbe Eko.

Alemu ko yẹ agba,
ki agba mașe ehun alemu.

Gbami-gbami ko yẹ agba, kinikan nle ni bowa ko yẹ Ọdẹ.
(Owe Yoruba).

## Barika Re Sardauna



Irohin kan wa wipe ọlọla Sardauna Șokoto ti o nșe Prime Minister fun ile awọn Hausa pada de lojọ [illegible] Mekka ni- [illegible] lọ fi oju kan [illegible] Muhamad ni Medina ki o to pada wa sile. Barika'o, Barika-[illegible]ika, oke Arafa ti o pun ati oke Tororo, Mina ati Safa si Mọriwa.

Alhadji to șeșẹ de Ba-da-amuda Ara Mẹkka ma ni Ba-da-amuda.

Ọrọ ọkunrin ọlọla yi lo fẹrẹ da edekoyede kan silẹ nilẹ Hausa lasiko kan. Ọrọ na lọ bayi wipe Ọlọla Nassar ti o nșe Primier fun ilẹ Egypt ni a gbọ wipe o mbọ wa bẹ ilẹ Hausa wo. Idirẹ ti a gbọ ni pe Sardauna lo s ọ pe ki o wa. Fun kini?





ORIKI BAMWO

Bamwo de, alajẹla ọmọde agbọmọla bi orișa, akọkọluko ogun ti nda'mọ l'ẹkun igbone, alata ogun ti np'o tuto rẹ wa rawara a jẹ bi idan, a gba bi ẹra ibọn. O s'abiku di ikugbagbe, o ș'ọmọ ti nhehin l'ore. Ikọ ri i sa, Ibo ko l'ọna tagiri. aiperi ri d'ẹkun lyọnu Olugbala l'ọmọ ti nyagbẹ ọrin o kapa inu wọ, o lu jẹdi l'alupa, gbogbo abiyamọ nyọ șẹșẹ, Ela ri i o roju. Ọrẹrẹ ri i o na'gbẹ bo'ra, Eyi npa'lẹmọ lodilẹsọ, ọrẹ ikoko, kosemani awọn abiyamọ. eni araiye nijado ri. O de'lu Ibo, o doga, o de'lẹ Hausa, o d'ọba, gbogbo Onișegun l'o sọ pe ko lẹgbẹ, gbogbo ọmọde lo nfẹ fun ilera.

*IGO KEKERE 2/6d IGO NLA 4/6d*
owo ẹkọ 1/6d fun igo kan.

THE EGBA TRADING
ARADAN STORES
18, Denton Bridge, Street,
P.O. Box 2, Ebute-Meta.


Printed & Published by The Eleti Times and Publishing Company, 28 Koseko Street P.O. Box 407 Lagos. Phone 1337.